**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbẹ l'ọrun gbọ. E o si mo otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.


# Irohin Yoruba


No. 814 JANUARY 11 — JANUARY 17, 1961 KOBO MEJI (2D)






Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri Ile-egbogi


# ERE ẸYỌ ADAMUORISHA DUN




Eyi ni aworan awọn ẹyọ ti nwọn ṣere l'Eko. Wo oju ewe kejila fun irohin ati aworan yoku.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni awọn elere ẹyọ Adamuorisha ṣere fun iranti awọn ologbe Ọlọla Kitoyi Ajasa ati ologbe Ọgbẹni Herbert Macaulay (Ejo-ngboro) lati fi aṣeyẹ yi kasẹ ajọyọ ominira ti a gba ni ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun ti o kọja.


(Wo oju ewe kejila)


# Alafin yan Esuọla Akano ni Bashọrun Ọyọ

## Oji nla wo ile mẹriula

IKALA, LẸSA IMUSHIN.

NI ọjọ Aiku ti i ṣe ọjọ kọkanla oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni ijamba ojo nla kan ṣẹ ni ilu Ikala, lẹba Imushin, Ijẹbu Ode. Ojo na bẹrẹ ni agogo meje aṣalẹ, ko si pẹ ti o bẹrẹ si ro ni oji nla tun bẹrẹ si fẹ, o si ka panu ori ọpọlọpọ ile lọ larin ilu. Ile mẹrinla ni oji nla na si ṣe l'ofo.

Opolopọ awọn enia ti ojo na ba dukia won jẹ ko si nile nigbati ojo na bẹrẹ. Elomiran ti jade lọ si ode, ogunlogo si wa ni ilu miran. Gbogbo awọn enia wonyi lo padanu nkan ini won.

Agbara ojo na pọ, omi ojo na si mu enia lẹsẹ to ẹsẹ meji. Ojo ati iji na baana nkan pupọ. O si pẹ pupọ ki oji na to duro.

Opolopọ enia ni ko ri ibi sun l'alẹ ọjọ na. Elomiran sun si ita gbangba ...

## Atọka

### Wo


Ọrọ Evangelist Akande 4

Akibu Alarape 5

Itan iṣẹdalẹ awọn Ọba ilu Iwo 8

Akede Ọna Igbala 9

Alapara Ibadan 10

Akiyesi awo irawọ nipa ọjọ-ibi 11


**NINU awọn ọmọ Oloye pataki ti nwọn du oy Bashọrun Ọyọ ni Alhadji Bello Oyewusi ati Esuọla Akano, ṣugbọn asẹh nwa-asẹhinbọ ẹniti Ọba Alaiyeluwa Gbadegẹshin, Ladigbolu Keji Alafin Ọyọ fi ọwọ si pe ki o jẹ oye Bashọrun Ọyọ na ni Esuọla Akano.**

Idi ti Alafin fi ri pe Esuọla Akano ni ẹtọ a ti jẹ oye na ju Alhaji Oyewusi lọ nipẹ nwọn ti ṣe eto kan ni idile awọn ẹbi Oloye Bashọrun pe ẹnikẹni ti baba rẹ ko ba jẹ oye Bashọrun Ọyọ ri awọn ko ni gba pe ki o jẹ Bashọrun le awọn lori.

Alafin si tun ṣe alaye pe nwọn ti fi iwe kan sode gẹgẹbi akiyesi pe ọmọ Oloye ti o ba fẹ jẹ oye Bashọrun ki o kọ iwe si Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọyọ larin ọjọ mẹrinla, ṣugbọn baba Alhaji Bello Oyewusi ko ṣe be ẹ, ati wipe baba Alhaji Oyewusi na ko jẹ oye Bashọrun ri. Alhaji Oyewusi ni o kọwe si Igbimọ lati jẹ oye na.

Ọgbẹni Esuọla Akano nikan ni o si yege ninu eto oye jijẹ yi, nitoripe o kọwe si Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọyọ ati pe baba rẹ si ti jẹ oye Bashọrun ri. Idi ni eyi ti o fi ni ẹtọ ju Alhaji Bello Oyewusi lọ lati jẹ oye Bashọrun Ọyọ.


WO OJU EWE KEJE FUN AKIYESI PATAKI




ESUỌLA AKANO

## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# Bi enia ba nyọ ilẹ ẹ da ohun abẹnu a ma a ṣe oluwarẹ

OLOTU Iwe Irohin Yoruba, ẹ si ku-ewu ọdun Keresimesi yi o. Gbogbo ẹnyin alabaṣiṣẹpọ Olotu na ẹ nlẹ mbẹun o? Gbogbo ẹnyin onkawe wa na kakiri gbogbo agbaiye, aṣeyi-ṣ'amọdun o.

Gẹgẹbi akọle oke iwe wa ọsẹ yi, laiṣe ẹmi ọrọ ni gigun, o fẹrẹ dabi ẹni wipe, arun kanna ti o ṣi nṣe ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹnia lode oni dabi owe awọn Yoruba kan ti o sọ bayi wipe:— "Kaka ki o san lara iya ajẹ, nṣe ni o fi gbogbo ọmọ inu rẹ bi obirin".

Kaka ki o san diẹ lara awọn ọmọ enia lode oni, pipele ni o tun npele si i. Bi ẹnikan ba sọ wipe ti on pọju lode oni, bi oluwarẹ ba tun ri ti ọmọ ẹlomiran, yio ṣọpẹ fun Ọlọrun Ọba Oga Ogo.

NWỌN NKIGBE

Awọn ẹniti o lowo ninu ọmọ enia nkigbe pe, nkan ko ṣẹnu're' ki a ma ṣeṣe so ti ọmọ enia ti o ji lai b'okoo ji. Bi awọn ọlọla ti nkegbe lode oni, awọn talika na ko sinmi. Okẹ aimọye awọn obirin nṣipopada ni ojojumọ aiye nitori boya a je san aibalẹ; ọkan ti joko kalẹ lọkan gbogbo awọn ọmọ enia.

Ṣugbọn ẹ ma gbagbe o bi enia kan ba nyọ ilẹ da, ohun abẹnu a ma a ṣe oluwarẹ. Lagbaja ni o nṣe mi ni ko jẹki nlowo-lọwọ. Lakaṣegbe ni ko jẹki ngrọmọ gbe pọn, a tilẹ ṣiṣẹ ohun titi, a ko ri nkan kojọ; a tilẹ tun ko owo ọhun jọ tan, a ko tun mọ ọna ti gbogbo owo ọhun ngba lọ tan porongodo. Laiṣe ani-ani' gbogbo ẹnyin onkawe wa na ni yio ti mọ wipe bayi ni gbogbo nkan nṣẹlẹ larin ọpọlọpọ awọn ọmọ enia lode oni.

Ṣugbọn nkan ti o ṣeni laanu ni wipe, sibẹsibẹ na ẹwẹ, oju ti ọpọlọpọ awọn ọmọ enia iba ma a fi riran, ni nwọn fi ntẹlẹ, atẹlẹsẹ ti nwọn iba ma a fi tẹlẹ lode oni, ni nwọn sọ di oju iriran.

Nwọn ti gbagbe wipe 'lagbaja ni o nṣe mi kan ko si, ọkan ara nyin ni ki ẹ lọ yẹwo kinnikinni, ki ẹ si mọ wipe: Bi ẹnikan ba ti nyọ ilẹ da ohun abẹnu a ma a yọ oluwarẹ ṣe.

ONIJAMBA

Nwọn ni bi enia kan ti wulẹ ki o mọ ọna ijamba to, iwaju ni oluwarẹ yio ba Ọlọrun Ọba, bi ọpọlọpọ awọn enia ti nfinu ṣika lode oni to, bẹni nwọn tun nfi irahun gẹgẹbi olotitọ fi ara han gẹgẹbi enia rere.

Bi nwọn ba si ṣe buburu tan, nwọn a tẹṣẹmọrin, nwọn a yara ma a lọ, awọn abunitan fi gbogbo ara ki ni. Bi nwọn ba fi oju kan ara wọn, nwọn a dabi ọrẹ kori-kosun, bi ẹnikan ba si pẹhinda tan, nwọn a dabi "ọta ọrun ko gb'ẹbọ" si ara wọn.

Gbogbo alamu ọmọ enia ni o dọbalẹ lode oni, a ko mọ eyiti inu nrun. Ṣugbọn ẹ ma gbagbe o! ọmọ enia mọ nkan idaru nitootọ, ṣugbọn Ọlọrun mọ ọ to, ko si ẹniti yio ta ọja ẹrupẹ oluwarẹ ko ni gba owo okuta.

Nwọn ni "awọ fẹlẹfẹlẹ bo inu, ko jẹki a ri ikun awọn abinu-ẹni" ṣugbọn sibẹsibẹ na, bi enia kan ba nfi ojojumọ aiye ta ọfa soke, ti o nyi odo bori; bayowu ki o ti le pẹ to, bi enia kan ba nyọ ilẹ da, ohun abẹnu ko ni ṣai ma a yọ oluwarẹ na ṣe.

ẸKUN LONI AYỌ LỌLA

Ọpọlọpọ ọmọ enia ni o ti fọn-fọn; fọn-ọn; fọn-ọn; ti ko dun, lode toni, ọkẹ-aimọye ọmọ enia si ti fi ojojumọ aiye tẹ ẹ, tẹ ẹ, ko 'yanu. Melomelo ni a si le ka ninu awọn oke ti o ti gaju ti ko si ga rara mọ lode oni? Melomelo si ni awọn ọkọ ti o ti jagun ri, ti ko si jagun mọ?

Ọpọlọpọ ogẹdẹ ti o ti nso bi agbagba ni o pada di nkan ti o tun nsọ wẹwẹ. Ọkẹaimọye igba-atẹ ilẹkẹ ni o ti pada di igba-atẹ ọrunla. Bi ọmọ araiye ba nsunkun loni' nwọn a tun pada rẹrin lọla. Ibanujẹ lọwọ ọtun aiye, ayọ lọwọ osi.

Bẹ ẹ si ni, ko si nkan meji' awa na ni a bẹrẹ ti a fi apo rẹ, nigbati o naro tan; ọwọ ko to apo mọ. Tabi ẹnyin na ha kọun bi o? Ọkunkun ko sa le kun, ki oninu ma mọ inu ara rẹ? Njẹ, bi nwọn ba ngbadura fun wa lode oni wipe, ki Ọlọrun jẹki a jere iṣẹ wa, njẹ gbogbo wa na ni a le fi gbogbo ara ṣe ami tinutinu si iyẹn? Njẹ, nigbati nwọn ba ha si ṣe adura fun ọmọ enia wipe, "Iwọ yio jẹ ere iṣẹ ọwọ rẹ lagbara Ọlọrun" ṣugbọn ti oluwarẹ ko le ṣe ami, njẹ nigbana, bawo ni nkan na ti ri ni?

Tabi ẹniti o wa nfi ojojumọ gbero aidara si ọmọ-

(Wo oju ewe kẹjọ)


Ki ọpa-ẹhin le
tọ-rọrọ ki
tapa-titan si
lagbara dada
FUN ỌMỌ
RẸ NI




OSTERMILK

Ile iṣẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni o nṣe e.

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2010. Lagos ati pelu ni ABA ati KANO

# Igbimọ oluwadi ofin Agbalaiye ṣ'ipade l'Eko



IGBIMO awọn Oluwadi Ofin Ijọba Agbaiye pari ipade nla won nilu Eko ni ọjọ Abameta ti i ṣe ọjọ keje oṣu yi. Nwọn bẹrẹ ipade won na ni ọjọ Iṣẹgun ti i ṣe ọjọ kẹta oṣu kanna. Gbogbo ilu agbaiye lo ran aṣoju wọn wa sibi ipade na, nwọn si sọrọ pupọ nipa ẹtọ ti awọn ara ilu ni nipa ofin. Aworan ẹgbẹ osi yi ni ti igbati Ọlọla Adetokunboh Ademola, Adajọ Agba Apapọ Ijọba Naijiria nki Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria ku-abọ nibi ipade na. Aworan isalẹ yi ni ti igbati Alhaji Mudathir Dindey ti ngbe opopo Idumagbo Avenue, l'Eko nṣe ikomọ laipẹ yi, Alhaji na lo wa larin pẹlu ọmọ lọwọ rẹ. Aworan isalẹ patapata lọwọ osi ni ti igbati Ọgbẹni Mustafa ati Omidan Iyabọ Bakare nṣe ti igbeyawo l'Eko, ti nwọn si nfi owọ le Kurani lọna isin Musulumi. Aworan ọwọ ọtun ni isalẹ patapata ni ti igbati Ọgbẹni John A. Pariọla, ọkan ninu awọn olukọ ile-ẹkọ giga (St. Finbarr's College) l'Eko ndagbere fun aburo rẹ Taiye Pariọla ki o to ba ọkọ ofurufu lọ si ilu Oyinbo fun ẹkọ giga.






## Ko si Ẹsanra ati irora mọ!

**Mu alafia rẹ lojojumọ**



**Ki o si fi opin si**

- ★ AIRIGBẸYA
- ★ ITỌNU ẸDỌ ATI ERE
- ★ INU-RIRUN
- ★ INU-ṢIṢU
- ★ ABAWỌN-ARA PATI-PATI
- ★ IRORA LAKUREGBE
- ★ IREWESI

FUN ILERA TITUN ATI OKUN-INU

**TISANE de DURBON**

Ma a fi ojulowo a ninu apoti pupa didan!

**Agbayanu Egbogi Atẹjẹṣe**

D.P.I. LTD. 1, AERODROME ROAD, P.M. BAG 1006 APAPA


## Awọn ọmọ ile iwe Elepo ṣe ere aladun

ELEPO-IWO.

GONOỌ sọ ni ilu Elepo ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu ti o kọja yi nigbati awọn ọmọ ile-iwe "African Church School", Elepo lẹba Iwo ṣ'ere ipari ọdun gẹgẹbi aṣa wọn. Ere na dun to tobẹgẹ ti o fi jẹ wipe gbogbo awọn bi ẹgbẹrun enia ti nwọn wa woran ni nwọn nyọmbo awọn elere na titi nwọn fi mu ere wọn wa si opin.

Ọgbẹni Adeoye Adesanya, Alaga ọjọ na si kan saara si Ọgbẹni J. Ade. Ajala ati awọn yoku fun iyipada rere ti nwọn ṣe si ile-iwe na, o si gbadura pupọ fun wọn.

# CLASSIFIED ANNOUNCEMENT

sowo ko awon iro-
ti o wa ni isale yi
a ko awon iro-
ba ri gba ti awon
ba si fi sowo si wa
owo titejade sowo
gegbi akiyesi ti a
ninu iwe "Irohin
" ose ti o koja.
a be gbogbo
nkawe wa lati tele
gegbi akiyesi ti

OLOTU.

* *

OJU, SHOGUNLE.

Aiku ti ise ojo

yi ni Ogbeni B. A.
so omo re titun
ko ni ile re. Iro-
to afojuba ni eye
Bi awon alaba-
po to ni Ogbeni
n jije ati mimu te
un. Nwon so omo
bdul Raufu Ola-



IGBOBI.

LAIPE yi ni Ogbeni Adewunmi ti nsise ni ile itewe Reluwe ni Ebute Metta ko omo titun ti Olorun fi ta on ati iyawo re lore jade. Nwon so omo na ni Adetayo.

* * *

IKIRUN.

OGBENI Nasim Akanji ko omo re jade ni ojo Ojobo ti i se ojo kewa osu kokanla odun ti o koja yi. Oruko omo na nje Serifatu Abike. Alfa Musitafa lo se eto isin isomoloruko na, awon alabaseye ojo na po pupo.

* * *

ABULE OFFA, AJILETE.

IROHIN ko ko afojuba ni ti inawo isomoloruko ti Alfa Lasisi se laipe yi. Oruko omo na nje Abudul Rashidi. Alfa Arikewuyo ti i se egbon baba omo na se inawo nla lojo na. Awon onilu si fi kokoro ilu won dabira lojo na pelu.

* * *

EKO.

ESE awon gbajumo lo pe sibi aseye ti ikomojade ti Ogbeni Busari se ni ile re lenuloloyi. Nwon so omo na ni Nono Awawu. Orisirisi awon egbe lo wa sibi ikomo na. Baba omo na ati iya omo na ti oruko re nje Moriamo Akonke si fi jije ati mimu te awon alabaseye lorun.

* * *

PRAMKESE, GHANA.

AWON enia po pupo to wa sibi aseye isomoloruko ti Ogbeni Abraham Akano omo Igosun ati iyawo re Iyaafin Esther Omosholape Akano se laipe yi ni ile won. Nwon so omo na ni Deborah Omolayo.

Alfa J. O. Adeniyi lo se eto isin isomolaruko na. Lehin isin, baba omo na fi jije ati mimu te awon alabaseye lorun.

* * *

OFFA.

OGBENI Salau Adebisi ko omo re okunrin ti Olorun fi ta on ati aya re lore jade lenuloloyi, ni ile Elerin Offa. Ese awon gbajumo, awon bi Ogbeni Disu (Alaga); Salau Alabi; Adeyemi; Alidu Alabelewe; Jimoh Ango; Alhadji Akere ati Omidan Nimota ni o pe sibe, nwon si so omo na ni Tajudeen.

Baba omo na fi onje ati oti te awon alabaseye na lorun, Ogbeni Buraimoh Aloyin si fi kokoro ilu re dabira lojo na. Aseye ojo na dun, o larinrin.

* * *

KANO.

LENULOLOYI ni Ogbeni A. O. Baruwa ti nsise ni Kotu Ijoba Ibile Kano ko omo re jade. Ni ile won 8, Festing Road ni nwon gbe ti se ikomo na. Ogbeni E. O. Banjo ni o se alaga, aya re si ran an lowo, nwon so omo na ni Olatunde Adisa.

Baba omo na fi orisirsi onje adidun te gbogbo awon alabaseye ojo na lorun titi ile fi su.

Awon Ogbeni L. A. Rafiu, J. A. Odusanya; Aremu Ilori; Y. A. Dosumu; O. Aiyelawo; Joseph Ogundele ati Alhadji Akiyode wa ninu awon alabaseye ojo na.

* * *

NGURU.

ESE awon ebi ati ore Ogbeni Usumanu Daudu lo pe sibi inawo ikomo omokunirn ti Olorun fi ta on pelu iyawo re Iyaafin Amudatu Daudu lore lenu loloyi. Alfa Yesufu Akande lo se eto isin isomoloruko na ni ona esin Musulumi; nwon si so omo na ni oruko Abudu Ganiyu Agboola.

Egbon baba omo na ti oruko re nje Momodu Daudu wa lati Kano, o si se inawo pupo lojo na. Bena ni egbon baba omo na keji, Nasim se inawo pelu.

* * *

ANIYIAM, GHANA.

NI ojo Abameta ti ise ojo kerinlelogun osu ti o koja yi ni Alfa A. O. B. Akewusola ko omo ti Olorun fi ta on ati iyawo re Aminatu Arinpe lore, nwon si so omo na ni Rekiatu. Alfa Musa Imam ni o se eto isomoloruko na ni ona esin Musulumi. Baba omo na si fi jije ati mimu te awon alabaseye ojo na lorun.

Ninu awon alabaseye ojo na ni awon Ogbeni David Adedokun, Musa Omoloso, Salami Oyebanji, Iyaafin Safuratu Ajogbe Adisatu Asunke Asimawu, Awawu ati awon enia ja-nkan ja-nkan lati origun mererin Ghana.

* * *

IGANNA LEBA OYO.

IROHIN ko to afojuba ni inawo isinku ti Omo-oba David Sulola Atoyebi Folawiyo Omo-Alokolodo Iganna se ni ojo Aje ti ise ojo kerindilogbon osu kejila odun ti o koja yi, fun oku aburo baba re ti o jalasi ni owuro ojo Aiku ti nse ojo kedogun osu na.

Inu gbogbo awon oloye ilu ni o dun si omo Oba Folawiyo, nwon si fere si owo na fun un nigbati o jo de ile won ni okookan. Die ti a le daruko ninu awon alabaseye ojo na ni awon Ogbeni Adesojie, Alaga Eka Egbe Afenifere, Iganna, S. B. Arikewu, Ogunbode, Okunola, Salami Maiyegun, Lasisi Ayinde, Lasisi Adegoke ati Aderiyi Adeyemi.

Ehin oku yio dara o.

* * *

OBA, OSHOGBO.

OGUNLOGO enia lo ti nki Ogbeni Joshua Oyewole Ojo ku orire ibeji ti Olorun fi ta on pelu iyawo re lore laipe yi. Eyi ni o di igba keji lera ti iyawo re na mbi ibeji Ni ojo idawo awon ibeji na, ile Ogbeni Gabriel Ojo ti i se baba fun baba ibeji na ko gba enia. Aseye ojo na po pupo. Jije ati mimu si te awon alabaseye lorun.

* * *

IKIRUN.

LENULOLOYI ni Oba Alaiyeluwa Lawani Adeyemi, Onikirun Ikirun fi Ogbeni T. Are. Oroge je oye Ekerin. Lehinti nwon ja Ewe Oye le e lori tan ni nwon wa yin iki ibon mokanlelogorin fun ayesi Oloye na, larin ogunlogo awon omo Egbe Afenifere ati gbajumo ilu, awon bi awon Ogbeni Tijani Akanni; Titilayo; Popoola Olaiya; Buraimoh Ajiro; I. O. Ogunronbi; Nasiru Adigun ati T. O. A. Olorisade.

Aseye ojo na dun o larinrin, irohin ko to afojuba ni. Oye a mori o.

**Ẹ ma a ka Iwe**
**IROHIN YORUBA**
**nigbagbogbo fun**
**irohin aladun**






# Itan iṣẹdalẹ awọn Ọba ilu Iwo

## Lati ọwọ Yẹkinni Lasisi, Iwo

ITAN iṣẹdalẹ awọn ọba ilu Iwo ti mo fẹ so yi bẹrẹ lati ori Ọba Lamuye titi de ọdọ Ọba Alaiyeluwa Abimbọla Keji, Oluwo Iwo ti o wa lori oye nisisiyi. Ki ade pẹ lori rẹ, ki bata si pẹ lẹsẹ, Kabiyesi o. Itan na lọ bayi:—

Nigbati Lamuye wa lori oye, bi ile ọba ba jọ ni ilu Iwo, awọn ara ilu rẹ ni yio kọ ọ, nwọn a yan awọn enia lati agbo-ile kọ-ọkan pe ki nwọn lọ pa korika, ki nwọn pa igi-akara igi-irole) ki nwọn si ja okun wa lati oko lati fi tun ile na kọ.

Bi nwọn ba mura tan lati ma a kọ ile na, ni inu agbala ni ọba na njoko si titi ti nwọn fi nṣe iṣẹ atunkọ ile na tan, awọn ẹmẹwa t' o ba joko ti i a si ma a fi abẹbẹ fẹ ẹ lara. Ọdun merindiladoje (126 years) ni Ọba Lamuye ṣe laiye ki o to w'aja.

ỌDUN MẸRIN —

Lẹhin ti Lamuye ku sori oye, Oshunwo ni nwọn fi jẹ ọba dipo rẹ ni Oke-odo. Nigbati ile oba si jo ba on na lori oye, nwọn tun pe awọn enia lati agbo-ile kọọkan jọ, nwọn si kọ ile Ọba na pada. Ọdun mẹrin ni Oshunwo ṣe lori oye ki o to ku.

Nigbati Oshunwo w'aja tan, Abimbọla Kini ni nwọn fi joye rọpo rẹ. Gẹrẹ ti o bọ sori oye tan ni ile-ọba ba jo, ni ẹkini, nwọn tun un kọ, o tun jo ni igba keji nwọn tun kọ ọ pada gẹgẹbi nwọn ti nfi koriko kọ ọ. Ṣugbọn nitori ki o ma ba a jo ni igba kẹta mọ ni Ọba Abimbọla Kini ba paṣẹ pe ki nwọn lọ ra igan paanu ikanle wa lati Teṣan Reluwe Iwo, nigbati nwọn ra paanu na de, o ni ki nwọn lọ ra igi Akoko wa lati Iju-Ọba lati fi ro ile na nwọn si ṣe bẹ ẹ.

> *Ẹniti o pa itan yi sinu iwe wa jẹ ọmọ ile iwe 'Methodist School,' Iwo.*

Lati akoko tirẹ na ni ile-ọba ko ba fi jo mọ ni Iwo titi di oni-oloni, ko si tun si wahala fun awọn ara ilu mọ lati lọ kọ ile ọba.

LUKU-LUKU

Lẹhin eyi ni aisan Luku-luku ba wọ ilu, nigbati wahala ti aisan lukuluku na si rọlẹ tan ni Ijọba bẹrẹsi gba owo-ori ṣile mẹfa (6s.) ẹnikọọkan ni Iwo.

Ọdun mẹtalelọgbon (33 years) ni Ọba Abimbọla Kini gbe lori oye ki o to w'aja, igba rẹ si dara pupọ fun awọn ara ilu Iwo. Lẹhin ti Abimbọla Kini ku tan, Sedu ni nwọn fi jọba rọpo rẹ ko si lo ju ọdun kansoṣo lọ lori oye ki o to w'aja.

Lẹhin ti Sedu w'aja tan ni Shittu ba gori oye, ṣugbọn nigbati o di ọjọ kẹta ti o gori oye ni awọn ara ilu ba lọ ka itẹ-ọba mọ ọ lara nitori nwọn ni ọna eru ni o gba gori oye. Rabọ-rabọ ija na ni o ba fi kuro lori oye patapata. Ni igba ọtẹ Shittu na ni awọn ara ilu ba bẹrẹsi korin ọtẹ pe:—"Oju ti Shittu o, ab'idodo o l'amọri. oju ti Shittu o" ati bẹ ẹ bẹ ẹ lọ.

Nigbati Shittu kuro lori oye tan ni nwọn ba fi Amuda jọba. Ni igba aiye Amuda ni nwọn da ọja Ararọmi ati ọja Kajọla silẹ. Ni igba aiye Amuda na ni nwọn da kotu Ibilẹ ti o wa ni Iwo nisisiyi silẹ. Nigbati Ọdun Ileya ku ọjọ mẹfa ni Amuda ba papoda lori oye nigbati o di ọdun kẹfa ti o ti jọba.

MỌṢALAṢI

Lẹhin iku Amuda ni nwọn fi Kosiru jọba rọpo rẹ, o si paṣẹ pe ki nwọn kọ Mọṣalaṣi kan si eti ile on, ni nwọn ba kọ Mọṣalaṣi na si eti ile ọba, ibẹ ni gbogbo enia si nlọ kirun Jimọh ni ọjọ Jimọh, ṣugbọn nwọn ko kọ Mọṣalaṣi na pari loju rẹ ki o to waja.

Ọba Kosiru kan na yi ni o kọ Ile Pẹtẹsi ti o wa ni Afin Ọba Iwo titi di oni-oloni, ọdun mẹtala ni o lo lori oye k i o to w'aja.

Ajani Adegoroye ni o jọba lẹhin iku Kosiru, ọdun mẹrin pere ni o ṣe lori oye ki o to ku.

Lẹhin iku Ajani Adegoroye ni nwọn ba fi Ọba Alaiyeluwa Abimbọla Keji, Oluwo Iwo ti o wa lori oye nisisiyi jọba ni ọjọ kẹta oṣu kini ọdun 1958. Ọba Abimbọla Keji yi ni ọmọwe kini, ti o jọba ni Iwo, aiye igba tirẹ ni nwọn fa ẹrọ omi wọ ilu Iwo ti nwọn si yọ ọda si oju titi ti mọto nrin ni Iwo.

Laipẹ yi ni nwọn yan an ni Minista ti ko ni ipinṣẹ kankan ninu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ki ade pẹ lori ki bata si pẹ lẹsẹ. Kabiyesi o.

## AKIYESI FUN ONKAWE

**Eyi ni lati so fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o ma a kọ ọ taara si ile iṣẹ re ni:**

**Allied Newspapers Limited,**
**Elephant House**
**214, Broad Street, Lagos**

## Bi enia ba nyọ ilẹ ẹ da

(Lati oju ewe karun)

ẹnikẹji rẹ ni yio ha le ṣe "Amin" si iru adura bayi bi? Tabi ẹniti o nfi ojojumọ aiye gbero iṣubu awọn eni-giga lainidi ni yio wa gbadura wipe ki on jẹ ere iṣẹ owọ on bi? Bẹni ẹgun ko si le gun ọmọ lẹsẹ ki o fa a yọ ni ẹsẹ ẹru.

Nwọn si ti sọ wipe, ogun ni o nṣini mu, ṣugbọn epe ati ire ki i ṣina. Nitori bẹ ẹ, laifa ọrọ gun l ọ titi mọ, bi iwọ ba wa ninu ipo ti o ṣe wipe, iwọ ko le fi gbogbo ara ati ọkan ṣe ami nigbati nwọn ba ṣe adura fun ọ wipe' ki Olọrun jẹki o jere iṣẹ owọ rẹ, nigbana ni ki o tubọ lọ yẹ ọkan rẹ wo finni-finni, ki o si tete mọ wipe:—Bi enia kan ba nyọ ilẹ da ẹtọ ni ki ohun abẹnu ma a ṣe oluwarẹ.

Olotu, a dupẹ o, o digba.


# Ọti Atẹjẹṣe Yi L'Oso Dejọ Di Elere Iyanu

*Ẹ Ka nkan ti ọti Atẹjẹṣe*

PHOSFERINE TONIC WINE *se fun Dẹjọ Fayẹmi ọmọ Nigeria ti o di Olokiki ninu awọn agbabolu*



Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹṣẹ, **PHOSFERINE TONIC WINE** Fun Ara Rẹ

*Kọwe si Phosferine Tonic Wine, P.O. Box 431, Lagos*

# Alapara Ibadan se ipinnu odun titun

ALAPARA—E ku owuro o? Olotu, e si tun ku-ewu odun titun ti o soju emi, ki Oluwa da wa si ki a le se opolopo re pelu alafia ati ayo.

OLOTU—Emi paapa ki o ku ewu odun titun na, ki adura odun titun ti o wa ninu Iwe Irohin wa odun yi le je ire ti Oluwa yio fi ohun si, ti yio se mo gbogbo wa lori.

ALAPARA—Ase. Amin, beni-ki-o-ri o.

OLOTU—Alapara, o ma to ijo meta ti a ti rira, se ko sa si nkan? Tabi ti igbadun odun titun yi na ni o fa o sehin?

ALAPARA—Gegebi imoran nyin, mo ti fi ara bale ronu igbesi-aiye, pe kini maa ti se ni iwa titun ti yio se anfani fun mi ati fun gbogbo eniti o ba ba mi lo ninu odun yi ju ti atehin wa lo.

OLOTU—Nje o ko mu oti amupara ni ale ojo aisun odun titun na?

ALAPARA—Ijewo ti mo se fun nyin nipa oti mimu mi bi o ti se po si ni ti mi loju pupo, ati pe, nigbati mo pada de ile mo



MLAPARA IBADAN

* * *

ronu titi mo si se ipinnu pe, ti o ba di ale ojo aisun odun titun, ma a jewo ese mi niwaju Olorun ti a ba dee Soosi, ma a si gbadura fun idariji ati pe, ki Oluwa pelu mi ninu ipinnu ifi-oti-mimu sile. nigbati a si de Soosi ni ale ojo aisun odun titun, mo mu ipinnu na wa si iwaju Olorun, mo si ni igbagbo pe Oluwa yio ran mi lowo ninu ipinnu na pe ki o mase tase.

OLOTU Nje nigbati odun titun yi ti bere. o koi ti mu oti rara?

ALAPARA — Nipa agbara Olorun, ileri na si duro be e, nitori nko iti ba enikeni sere de aye fi fi tombila oti dan enu mi wo, afi ti omi nikan.

OLOTU—Nje wa le pa ofin ipinnu re na mo titi aiye?

ALAPARA—Nko le so ileri nitori, mo ti se iru ileri be e ninu odun kan. Sugbon nigbati o to bi osu mefa lehin ipinnu na ni mo nse itoro iyawo kan, ni nwon ba si okan 'nu oti ti mo ra lo, nwon sure si i, nwon si bu gaasi kan fun mi pe ki ngba ire. Eyi ni mo fi to enu wo, ti nko fi le tun fi ara da a mo, ni mo ba tun bere si i mu oti die-die titi ti mo tun fi di 'baba-lami-lami' bi ti atehinwa. Nitori idi eyi nko ti i le so, afi bi odun yi ba pari ti mo si ri i pe, ipinnu na ri be e.

OLOTU—Bi o ko ba fe e fe obirin titun, bi obirin titun ba fe fe o nko?

ALAPARA—Obirin titun se le wa fe mi nigbati nko ba a ni oro tele-tele? Mo si lero pe, aiye ko iti baje de ipo pe obirin awa Enia-dudu, paapa awon omo-birin Yoruba yio le la enu re so fun okunrin pe on fe e fe e.

OLOTU—Bi ko ba fi enu so, ti o ba fi oju nso nko:

ALAPARA—Enyin agbalagba ni e mo gbogbo iwonyen, emi ko mo bi obirin ti se nfi oju soro si okunrin.

OLOTU—Bi o ba je pe, eniti ko ni obirin ni ile tabi ni obirin ri, ti o ba je Apon ni o so pe on ko mo bi obinrin ti se fi oju pe okunrin, mba gbagbo pe nitoto, ope ni o. Sugbon iwo ti o ti nahanbe-nahanbe nipa fife obirin, ti o si ti na pota-na-kalaba, ti o wa sese nso fun mi pe, o ko mo bi obirin ti se nfi oju soro si okunrin, nko gba e gbo rara, nje iwo paapa ko fi oju soro si obirin ri?

(Wo oju ewe kejila)







## AKIYESI PATAKI

Ki ifokanbale le wa fun eniti o ba fi iwe irohin ikomojade, isinku, igbeyawo, isile ati bebee lo sowo aiwa pe ki o jade ninu Iwe Irohin Yoruba. Bi o ba fe ki o jade ni oranyan ki o kuku se ni ipolowo oja, sile kan abo (1/6d) ni a ngba fun oro marun fun apere:— "Irohin koto afojuba ni aseye oku iya Moradeyo ti o se l'ojo kewa osu yi". Eyi je oro medogun, owo re si je sile kookanabo ona meta o je sile merinabo (4/6). Bi o ba si ti po to ni owo re yio fi po to. Oro marun fun sile kan abo (1/6) ni.

## ITUMO ALA

Eniti o ba si fi ibere itumo Ala re sowo ti o si nfe esi ni kiakia ki o fi sile meji abo (2/6) sowo pelu re si wa.

E ku ise o.

OLOTU

# Ere Ẹyọ Adamuorisha dun l'Eko



Aworan ẹgbẹ osi yi ni ti ıtẹku ọkan ninu awọn Ologbe pataki mẹji ti awọn elere Ẹyọ Adamuorisha l'Eko fi ere ẹyọ na ṣe iranti wọn lati fi kase ajọyọ ominira ti Apapọ Ijọba Naijiria gba ni ọjọ Abamẹta tı ıṣe ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun 1960. Irohin bi ere na ti ıa-rinrin si wa ni isalẹ aworan na loju ewe yi.

Aworan ẹniti nwọn tẹ oku rẹ ni ti Ọlọ̀a Ologbe Kitoye Ajasa.

(Lati oju ewe kini)

Lati bi ọsẹ kan sẹhin, ki o to to aseko ere yi ni awọn alaṣẹ ere ẹyọ Adamu-orisha na ti fi 'iwe akiyesi sode pe ni ọjọ Abamẹta ti i ṣe ọjọ keje oṣu kini ọdun yi ni awọn yio ṣe ere na. Lati igbana ni gbogbo enia ti si f'oju s'ọna lati ri ere ẹyọ na. Lati igbana ni awon elere paapa si ti ngmura silẹ gẹgẹbi nwọn yio ti ṣe se ti yio fi gbadun ti gbogbo enia yio fi yombo wọn.

Irohin ko to afojuba ni ere ọjọ na, nigbati awọn ẹyọ na jade onikaluku ọwọ awọn ẹyọ na jade lati idile wọn, gbogbo awon enia to wa l'Eko lo si rohin pe ere ẹyọ Adamu-orisha ti ọtẹ yi fẹrẹ dun ju gbogbo eyi ti nwọn ti nṣe latẹhinwa lọ.

Nigbati ere ẹyọ na ti ku ọtunla ni awọn alaṣẹ ere ẹyọ na ti tẹ oku awọn ti nwọn nṣere na ni iranti wọn—Ologbe Ọlọla Kitoyi Ajasa ati Ologbe Ọgbẹni Herbert Macaulay si Gbọngan Apejọ Glover ni Ehingbẹti l'Eko ti gbogbo enia si nrọ lọ wo wọn.

Gbogbo awọn to si lọ sibẹ lo nkan saara si awọn ti o ṣe eto itẹku awọn ologbe mejeji na..



DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.
Ṣa ti mu egbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ .........yio si ko rirogun omiro na kuro, a si lé irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.
Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'



Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS

ODARA FUN GBOGBO ẸBI

CLASSIFIED ADVERTISEMENT

NI IRANTI Arabirin mi Ologbe Iyaafin RAKELI GBOYINDE ADEDIJI ẹniti o jẹ ipe Ọlọrun ni ọjọ kejila oṣu kini ọdun 1960, ẹniti a ko le ṣai lai ranti gẹgẹbi ẹdun ọkan wa, ṣugbọn akuku fi aniyan ati ipade wa si ọjọ Ajinde. Abẹgbe Ose sunre—Joseph Bandele Adediji awọn ọmọ rẹ Maria, Rodah, Tinu, Taiye ati Kẹhinde, Kayode ati Ademola.

## Alapara

(Lati oju ewe kẹwa)

ALAPARA — Nko jiyan, mo ti nṣe bẹ ẹ ri nigbati mo si njẹ "ṣango-ode", ti nki i ti di "Ọya-inu-igba".
OLOTU—O ti to ọdun melo sẹhin nisisiyi ti o ti kuro ni "Ṣango-ode" ti o si wa di "oya-inu-igba?"
ALAPARA—Ẹ jọwọ fun mi laye, ki nsi ma a lọ na, ki nwa nigbamiran nitori oju nkan mi lati sure lọ si ibikan pa a!

OLOTU—O dara, ko buru o, oju ko ni fẹraku, o digba-o-ṣe o.

IKỌ - FEE
TI I DI ỌNA-ỌFUN
ỌJỌ KANNA NI
YIO DẸ

Maṣe jẹki iko-hihu, siasin, didi ọna ọfun ti ikọlu Ikọ otutu tabi ikọ-fee fi ọjọ kan tabi oru ọjọ kan ba orun tabi agbara ilera rẹ jẹ laiko dan MENDACO wo. Egbogi nla-nla yi ki iṣe eefin, abẹrẹ-gigun tabi fifọn, ṣugbọn ninu ẹjẹ ni o nṣiṣẹ, bayi ni o ti ṣe de inu ẹdọforo ati awọn iho-ọna-ọfun. Akọlo rẹ yio bẹrẹ si ran ara lọwọ lẹsẹkẹsẹ ni ọna mẹta: Ekini yio ṣe iranlọwọ a ti dẹ kẹlẹbẹ kiki ti o nfun ọ lorun, yio si yọ ọ kuro. Ekeji Bayi ni yio si fun ọ ni anfani mimi kalẹ ati pẹlu irọrun pẹlu orun asunwọra. Ẹkẹta, O nṣe iranlọwọ didẹ-ikọ, mimi tipa-tipa ati sisin. A se ileri itẹlọrun ninu ilo rẹ tabi ki o gba owo rẹ pada. Ra MENDACO lọwọ apoogun loni.

F'opin si irora
Lakuregbe
lati oju orun

Bi irora ba nda ọ laamu kikan-kan, bi awọn isẹpo ara rẹ ba wu, eyi fi han pe awọn kokoro-arun, omi-aisan ati aisiṣẹ deede Ẹrẹ (Kidney) ti ba ẹjẹ rẹ jẹ. Awọn apẹrẹ aisiṣẹ dogba Ẹrẹ (Kidney) ni ki ito ri rukuruku ki ito ma a jo ni nidi, ki iho ọna-ito ma a hun ni. "Ki a ma a diji loru". Ehin-didun, ojugun riro ni, ara gbigbọn, oyi, ẹfori, kokoẹ wiwu, ki oju ma a ta ibanba, ailokun-ninu ati bẹẹbẹẹ lọ. Egbogi lasan ko le ṣe iranlọwọ to nkan, o ni lati pa awọn kokoro-arun ti o nfẹ ba alafia jẹ. CYSTEX ni o le pa ile wahala wonyi mọ nipa yiyo gbongbo rẹ kuro. Ra CYSTEX lati ọwọ apoogun ti o ba ri lori adehun pe yio mu ọ lara da tabi ki o gba owo rẹ pada. Ta ṣaṣa nisisiyi! Larin wakati merinlelogun ara rẹ yio ya, yio si wo ọ san patapata larin ọsẹ kan.

Cystex

Fun awọn Ẹrẹ (Kidney) Lakuregbe, Ile-itọ.

Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" ọdun kan—Eko sile mejọ ati kobo mejọ (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. Ademuyiwa, 2 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.